# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA
No. 1,431 TUESDAY AUGUST 17, 1965 (2D)


IBADAN UNIVERSITY ... AUG 1965

## Isinku Omo-Oba Simbiatu Alake Kosoko Dun

EKO:— Irohin ko to afojuba ni isinku Omo-Oba Simbiatu Alake Kosoko ti o ngbe Adugbo Imaro ni No 28. Ni ọjọ keji osu yi ni Oloogbe na fi ile se aso bora. Hadji-Immam-Deen ti Mosalasi Ereko ni o si se isin ikehin fun un, ni ite Oke-Suna

Ese awon Alhadji-Immam-Deen, Immam, Ahujsj, Alufa, Olowo, Olola ati Borokinni ni o si pe sese si ibi aseye isinku na. Nwon to egbaagbeje enia Awon omo oku na ti awon si je gbajumo, awon bi Ogbeerin Rufai Olakunle Hassan, Mustapha Alade, Hassan, Adijat-Kubra Ogunlana ati Ayisat Ariori na wabiawosi owo, fun awon gbogbo awon alabaseye isinku na. Ajeti ni nwon fi onje se. Amuti, si ni nwon fi oti se

Eni ire ni Ologbe na, olufokanaan si ni o je ni igba aiye re. O ni oyaya, o si ko t'omode-t'agba mora. Suru re p O si lawo si awon alufa ati awon mekunnu. Ki Olorun dari ese re jin in Ki o si ke e, ki o ge e. Ki o si da awon omo re si fun ire.

# OBINRIN KAN FI OYUN ỌDUN MEJI BI EWURẸ!

IBADAN:— Gbogbo ilu lo gbojikan fun ariwo, awon ara ilu si bẹrẹsi sare akolukegba tele ara won nigbati nwon gbo agbayanu Irohin kan wipe, Obinrin aboyun kan, Iyaafin Abigail Omoyemi, eni adota ọdun ti o wa ni Ṣọọṣi Ijọ awọn Aladura kan ni Oke-Anu, Ekotedo, Ibadan ti bi 'mo ninu Ijọ na lẹhin igbati o ti ni oyun fun odidi osu merinlelogun sugbon nigbati Obinrin na bi'mo tan, ni nwon ni wipe eran ewurẹ ni Obinrin na bi ni ọjọ ọjọ 'Bọ ti ise ọjọ kejila osu yi.

Ha! se gbogbo awon enia ti nwon wa ninu Ijọ awọn Aladura na nigbati nwọn rii wipe, Obinrin na bi'mọ, ṣugbọn dipo ti nwon ki ba fi gbọ ohun ọmọ titun ki o maa ke, ohun ọmọ ewurẹ ni nwọn gbo ti o nke ni abẹ Obinrin na.

Bi awọn enia na ti gbọ ohun ẹran ẹwurẹ ti o nke labẹ Obinrin na ni gbogbo wọn ba bẹrẹsi sare dide pelu iyanu ariwo wipe, "Hẹ a ri omo ewurẹ ni di enia, iro ni, otito ni."

Irohin fi ye wa wipe, odun keji niyi ti Obinrin na ti loyun, atipe lati igba ti o ti loyun, n o t bẹrẹ si lo si ile Itoju awon Aboyun. ti o si nlo gba oogun ninu ile Itoju awon Aboyun ninu ilu won.

Ni agbo i l e Arunto, ni adugbo Iremo ni Ile-Ifẹ ni Ọmọ'ni tin na ti wa si igbo ro ilu Ibadan. O ti de s i Ibadan nisisiyi to osu mefa: siwaju ... ko yi ni Obinrin na ti nkiri kaakiri pelu oyun inu rẹ ti o si nti i ikan de ibi keji wipe bọya on y i o ri enit o le se iranlowo fun on nipa oyun inu rẹ ki o si le bi omọ ti o wa ninu rẹ ni aye tabi ni oku.

Onirohin wa Ejongboro ti o lọ si Ọyọ ni i ari ose ti o koja lọ yi fi ye wa wipe nigbati o de Ibadan ti on gbọ agbayanu Irohin na ni o ba sare sokalẹ ninu moto ti on si lọ fi oju ara on ri Obinrin na ti woli ti Obinrin na bi 'mọ ninu ṣọọsi rẹ.

Lẹhinna ni mo ba sare lọ si ṣọọsi n a ni ad gbo Oke-Anu ni Ekotedo Ibadan ti mo si bi Obinrin na ninu ṣọọṣi na pẹlu woli ti o wa ninu I ọ na Joseph Durojaiye eni ọdun merinleladọta.

Nigbati mo de inu ṣọọṣi na mo ba ẹgbaagbeje enia ninu ṣọọsi na ti awọn lọ si bẹ l ti lọ fi oju ara won ri Obinrin na

Gẹgẹbi akiyesi mi mo ri I wipe ki ise lati ri Obinrin ti o bi'mọ na nikan ni awọn enia se lo si inu ṣọọsi na fun

Awon miran lọ si ibẹ lati ri Obinrin na, awọn miran si lọ si ibẹ lati lọ fi oju ara wọn ri ẹran ewurẹ ti Obinrin na bi, bẹẹ si ni ẹwẹ, awọn miran tun lọ sinu Ṣọọsi na lati ri Obinrin ti o bi'mọ ki nwọn si tun ri ẹran ewurẹ ti o bi.

Nigbati mo de ibẹ, mo ba Obinrin na ti o kulẹ ni waju Woli Joseph Durojaiye ti o si ngbadura fun un. Awọn enia ti mo ba nibẹ jọ pupọ, ti nwọn ko si fun enia laye wọle, sugbon gẹgẹbi ẹnyin na ti se mọ wipe aye ki ha ki adiẹ ma de ibi ẹyin rẹ emi Ejongboro rapa la deibi ti Obinrin na ati Woli na wa

Ninu iforojomitoro oro pẹlu Iyaafin Abigail Ọmọyẹmi nipa ohun ti o ṣẹlẹ sii, Obinrin na so fun mi wipe,

"Ọdun keji ti mo ti loyun niyi Ko si ibiti nko ti de tan lati le ri ọmọ inu mi bi sugbọn ... gbo ibiti mo ba d asan ni gbogbo ohun ti n ọ nṣe fun mi

"Ṣugbọn laipẹ yi n ẹnikan s fun mi w p ki nkuro ni nu ilu wa ni Ile-Ifẹ Oluwa rẹ l ju e Woli Joseph D...

WO OJU EWE KẸFA

## Awọn Oṣiṣẹ Ti Pada Si Enu Iṣẹ



Aworan Oke yi ni ti awọn oṣiṣẹ ti nwọn da iṣẹ silẹ. Ka Irohin ni oju ewe kẹfa.

# ETO ILE FUN AWỌN OBI

Olotu, jọwọ gba mi ni aye ni wọn ita rarpẹ rinu iwe "Irohin Imọlẹ" eyiti gbogbo awọn ọmọ Yoruba nile ati ni ẹhin odi nkan daada nisisiyi lati le fun gbogbo awọn Obi l'Ọkunrin ati l'Obinrin ni awon Imọran diẹ eyiti mo ler wipe yi ṣe opolopo anfani fun gbogbo awon Obi, ti yi si tun fi ọna han gbogbo awon ti nwon ni anfani na ni ọwọ tabi awon ti anfani na wa ni arọwọto won, ṣugbọn ti o dabi ẹni wipe nwon ko mọ ilo anfani na tabi ti nwon ko mọ ib ti nwon lẹ lọ lẹhinti nwon ti bọ sinu wahala na tan.

O fẹrẹ jẹ wipe, yika gbogbo aiye loni, ni awon enia wa ninu wahala eto ile ṣiṣe, ti awon miran si tun wa ni nu aifaiyabalẹ on idaamu tọkọ-taya nipa ọmọ bibi.

Obi ni lati ṣe ni wipe, lẹhin igbeyawo, nwọn gbọdọ ṣe eto iye ọmọ ti awọn fẹ bi tabi iye ọmọ ti nwọn fẹ bi ni igbesi aiye wọn.

Eto yi ṣe pa aki lọpọlọpọ e lati ẹhin wa.

## BABA ONIKOBOKO



Awọn yi ko ṣe eto, nwọn si di alaini

Ọpọlọpo awon Obi ni wọn ti ṣe wahala titi nipa eleyi ti nwon ko si mo ibiti won le lọ, ti ọna si run poruru niwaju won nipa eto ile ṣiṣe fun tọkọ taya.

Eto ile ṣiṣe jẹ ọranyan fun awọn obi lati ṣe bi aba fẹ gbe igbeaiye ti o mu iro run ati iderun lọwo, ti yio si tun fun awọn Obi ni ifa iyabalẹ lẹhin ti nwọn ba ti bi'mọ tan.

Ọpọlpo awọn nkan lo wa ti awọn Obi ni lati ṣe, ṣugbọn ti ọpọlọpo wọn ko mọ. Eto ile ṣiṣe jẹ ohunti tọkọ-taya ni lati ṣe fun ara wọn ki nwọn le ni ifaiyabalẹ ati alafia ninu ile.

Ninu gbogbo awọn Eto wọnyi, ohun kini ti awọn fun gbogbo awọn Obi late, o si tun jẹọranyan rẹlu. Lọn kini, tọkọ-taya gbọdọ ṣe Eto ki nwọn si tun le bi ọmọ nigbati o ba wu awọn mejeji.

Ọmọ ki ise ohunti awọn Obi le maa fi agbara bi, bi igbati Ehoro tabi ekute-ile ba nbi ọmọ awon obi gbọdọ ṣe ẹto fun ile wọn kiwọn si mọ iye ọmọ ti awọn mejeeji fẹ lati bi.

Awọn obi miran tiṣe eto fun ile wọn ti nwọn si mọ iye ọmọ ti awọn mejeeji fẹ bi ngbati nwọn ba si ti ṣe eto na tan awọn mejeeji yio joko ro inawo wọn wo bi agbara wọn yio ba le ka iye ọmọ ti wọn fẹ bi.

Bi o ba jẹ wipe agbara wọn ko ni le ka ju ọmọ mẹrin lo ọmọ mẹrin na ni wọn yio bi nọ nwọn ko ni bimọ mẹrin ti awon mejeeji jijọ piunu lati bi lọ.

### Ẹkọ Iṣinlẹ

Lẹhinti nwọn ba ti bi ọmọ merin ti awọn mejeeji jijọ ṣe adehun lati bi tan awọn Obi na yio da ọwọ ọmọ bibi duro, nwọn ko si tun ni bi ọmọ mọ gẹgẹbi adehun tabi Eto ti nwọn ti

Bi ẹnyin na ba wo awọn awọn mejeji wọnyi, ẹo ri da ju wipe awọn Obi kan ṣe tofun le wọn, nwọn ni ifaiyabalẹ, awọn ọmọ wọn si dara, nwọn ni owo ọwọ lati a fi tọju awọn ọmọ wọn, le nni owo lọwọ lati le jẹ onjẹ ti o dara si inu arawọn, awọn ni agbara lati le tọju awọn ọmọ wọn awọn ọmọ paapa na mọ awọn Obi wọn ni Obi.

Nigbati asiko si de lati lọ si ile ẹkọ awọn Obi ni owo lọwọ lati ran awọn ọmọ won lo si ile iwe ti nwọn fẹ gbogbo awọn na ni nwọn si ni ẹkọjinlẹ eyiti o ye kooro

Bakanna ni awọn ti nwọn ko ṣe Eto fun ile wọn bẹrẹsi bi ọmọ, bi Ehoro, nwọn bi igbati ekute ile iba maa bi'mọ, nwọn ko ṣe Eto fun ile wọn.

Nitori idi eyi, awọn ọmọ wọn le ni ifaiyabalẹ, awọn Obi na ko ni owo lọwọ, nwọn ko le ran ọmọ wọn lo si ile ẹkọ giga, bi nwon ba si ran awọn kan lo si ile ẹko nwon a fi awon yoku silẹ.

Ni ọpọlọpọ igba ni ebi maa npa ọmọ won nitori na ko ni owo lowo lati ra onjẹ silẹ fun awon omo wọn jẹ nigbati ko ba si itoju fun awọn omo to gbogbo wọn ko ni le di ọmo rere lẹhin ola nwon ki si le di eni a arara.

Gẹgẹbi owe awọn agba ti o so wipe "Ebi ki wo nu kl oran miran ko o wo ati wipe a ko si owo lowo ni baba ijẹrẹa igbati awon omo ba po tan ti awon obi ko ba si ni owo lowo lati le toju won awon omo nako tilẹ ni gbo ti awon obi won.

Nigbati awon ọmo ko ba si gbo ti awon obi nigba na ni awon iru awon omo na yio maa lo sinu ni ita awon miran aya omojaguda awon miran a di onijagbon awon miran aya kolekole agunbẹ odaran apanin ati oniruru omo ti ko gbo ti awon obi.

Ṣugbọn ninu eto wa yi, a o here mẹa si fun gbogbo ẹnyin onkawe wa ona to dara lati maaṣe eto fun ile wa ati iru ona wo lo dara lati gba ṣe eto na ati ni ipari, iru eto wo lo yẹ ki a ma ṣe fun ile wa ti ile wa yio fi ro juti odẹdẹ wa yio si fi toro lẹhin ola

Bayi ni a duro ni ọsẹ yi ṣugbọn ẹ ma gbagbe wipe a o tun ma ka oro wa yoku lọ ni ọsẹ ti nbọ bi Oluwa ba da emi gbogbo wa si iyo ko tun di ọsẹ to nbo o



Awọn yi ṣe eto nwọn si ni ifaiyabalẹ

WANTED

Males & Females advertisement Canvassers on Commission basis

*Apply in Person to* Advertisement Manager

IROHIN — IMỌLẸ

16, Bamgbose Street Lagos,

# Ẹgbẹ Dẹmọ Ti Di Aja To F'ori Ko'mi

LATI ỌWỌ **Olanipẹkun Oki Ibadan**

Ẹgbẹ Dẹmọ orun
Ẹgbẹ Dẹmọ ti di iku ọjọ kẹfa; o wa nyan kiri ile
Ẹgbẹ Dẹmọ ti di ohunti ọmọde nri Sa
Ti awọn agbalagba si nri poşe şaraşa
Ile ti a ba fi iọ mọ iri owurọ ni wo o
Ẹgbẹ ti a ba fi idi r n g e kalẹ o yẹ ki o pere patapata
Ẹgbẹ ti o ngbero lati pa ẹgbẹ miran rẹ
Nitori ki o le duro, ẹgbẹ buburu ni,
Ọrọ iwe mimọ ko gbodọ ma şẹ ti o wipe;
Ẹnikẹni ti o ba fẹ fi jamba di olori,
On na ni yio şe akobata fun awọn yoku
Ẹgbẹ Dẹmọ ji ọmọ ẹgbẹ Ọlọp;
Ẹgbẹ Dẹmọ ji ọmọ ẹgbẹ Alakukọ
Ẹgbẹ Dẹmọ a ile onile bo tirẹ lẹhin nitori ki o le duro
Kaka ki ẹgbẹ Dẹmọ duro wiwo ni o nwo si lojojumo
Ẹgbẹ Dẹmọ nrin nitoripe ni asiko ti awọn ni inira de
Ko si owo lode
Ko si işẹ lode
Ọja ko ta
Orun ran laranju
Ojo nrọ ko da
Iku ọmọde ko lopin
Iku arugbo koja la
Iku gbaju nọ p, olowo nku pẹlu
Gbajumọ wẹ'wọn,
Ọba nku Ọmọwe wewe k ja lojiji
Agbako ni g a yi ẹ fu gbo bo enia
Akoko ẹgbẹ Ọ.ọpa ko ri bayi

Nigbati Ọlọrẹ wa ni Ijọba aiye rọju Ilu raye.
Işẹ şişe pọ owo si pọ bi o ti ye
Ko si ole jija bi ti igba iye Dẹmọ yi
Oja ta bi o ti yẹ, ko si si ogun tabi ọtẹ
Bẹẹni ko si si ifi pamuni, Bi ọmọ ẹgbẹ Ijọba ti nrin.
Bẹẹni ọmọ ẹgbẹ Alatako nya
Awọn enia ti nwọn ta daran ti nwọn n wọn.
Opolopọ awọn enia ni a nju si ẹwọn lagba dajọ
Ẹniti o ba ri Dẹmọ ti ko sa
Sotia ti da Oluwa rẹ
Bi aja ba fi ti kon i ọna agba a
Ẹ yago fun Dẹmọ
Ẹgbẹ Dẹmọ ti fi ori ko mi O
Ẹ DIBO FUN UPGA

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Maşe jafara pẹlu işẹ rẹ, ki o ma si şe jẹki inu rere fi ọ silẹ, Ore şişe ri yio sọ ọ di eni atata.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Ire ni gbogbo ọjọ oni yio jẹ fun ọ jẹ lẹ ki o mura lati gba alejo pataki ti yio kan ọ l ra l ni.

ARIES (Mar 21-April 20) Sa gbogbo agbara rẹ ki o maşe jiran tutu loni, bi o ba tilẹ şe şe, maşe sunmọ obirin loni,

TAURUS (April 21-May 20) Maşe k ura bẹni ki o maşe şagidi ki ile ọjọ eni ba le j tirẹ jale.

GEMINI (May 21-June 21) Maşe jẹki ere şişe pọ ju ọ lọ lẹ nu işe fi ọkan sibi işẹ rẹ, ki o le ni ilọsiwaju.

CANCER (June 22 July 22) Ọti mimu ko le şe ọ ni anfani kan nitori a şọra nidi Ogokero ati Bia, ki o ma ba di baraku fun ọ.

LEO (July 23-Aug 22) Maşe ta fele-fele niwaju mọto loni, ki o ma si şe jẹ ẹniti yio ma ronu bi o ti nrin lọ.

VIRCO (Aug23:Sept23) Atẹgun yio pọ loni maşe fi ara si atẹgun pupọ ki o ma ba şaisan ti yio ko idiwọ ba işẹ rẹ

LIBRA (Sept24:Oct 23) Maşe lọ si irin ajo loni k i o si jẹki i u rẹ dun si gbogbo eni lo ni şe itọju awọn ... ki alafia si lọ ọ

SCORPIO (Oct21:Nov22) Şe saru ki o si ni ifori ti nitori ẹniti a ba nfẹ irẹ ki binu agba ti ko binu ni ọ m ọ rẹ nigo

SGITTARUS (Nov23:Dec21, Maşe şahun si ẹnikeni ni ki o si maşe irorẹ aan nit nipe ninu rẹ ni ire tirẹ wa

CAPRICORN (Dec22-Jan21) Şọra nipa ajẹki a ti wọra ki o ma ba fi eju ro je ijeku je Ẹsọ di owa re o,

GBANGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!! BI INA WỌLE OKUNKUN YIO PARADA IYẸN DAJU




BERE EGBOGI TUNTUN TI WỌN NPE NI :—

"DROSELIA"

Meji rẹ kosi ni igboro Ilu Eko tabi Nigeria

Bi amodi "IKỌ" ti ọ rẹ ti pẹ tabi ti o ti to nkan bi ọdun ka tabi jubẹ lọ, awọn egbogi rẹbirọhi ti wọn nta kakiri ti bi opolọpọ ni orişirişi ko le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ şe ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara ilu Faranşe ti nwọn npe ni "DROSELIA" o u owo hauhaun atamatase egbogi fun Ikọ ẹgb, Ikọ Aipeti, Ikọ Awugbọn Ikọ Awugọn Ikọ ọnọfun, Ikọ lile. Ikọ ti o mọ mu enia tirin pẹlẹbẹ nigb kugba lati i ji "Ifun wa (Lungs) tabi ikọ ti awulaogun lọsan tabi loru ti o si ma nmu ki enia ma gbẹ ta bi tiru lara pẹlu. Bi o ba dan Igo kan DROSELIA wio Iwọ na yio ri iyatọ nina ara rẹ ni ... Igba aya rẹ b ọna ọfun re ti o ... yio duro "IKỌ" re yio sisan patapata iwọ yio si ... a jẹun daradara, iwọ yio si sun fọn fọn pẹlu, alafia de si ọ. Bere egbogi yi ati awọn orişi rişi Egbogi I ọ mi ran ni Şọbu awọn:-

NIGERIANMEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street Lagos
Phone 22878 (Oja Itẹ Faji)
ATI NI ŞỌBU
IŞẸ OLODUMARE DISPENSARY OKEBỌLA
IBADAN

# Ẹgbẹ Ọmọ Ọlọfin Ṣe Ipade

IPỌNRI ALAKA EKO:- Enia pọ bi ewe rumọ ni ọjọ ti awọn ẹgbẹ Ọlọfin ṣe ipade gbogbo gbo o ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi ti gbogbo wọn si pa ẹnu pọ dupẹ ti nwọn tun fi imore nwọn han si gbogbo awọn Ọba ile Yoruba Ijoye paapa Dokita M. A. Majẹkodunmi ti o jẹ asiwaju ẹgbẹ na Oloye H. O. Davies ti o jẹ akowe agba fun wahala ti nwọn ṣe lati jẹki awọn ọmọ Yoruba le jẹ ọkanṣoṣo.



Oloye Majẹkodunmi

Ọgbẹni Ọlatunji Okunowo ti o ba awọn ẹgbagbeje ọmọ ẹgbẹ Ọlọfin sọ ọrọ ni ijọ na sọ pe ete ati ero ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin ni lati tun iṣọ gbogbo ọmọ Yoruba di ọmọ iyakan lai ka ẹgbẹ oṣelu ti nwọn le wa si lati ni abayọri rere fun iṣọkan ile Yoruba o wa rọ gbogbo enia to ngbọ ọrọ rẹ pe ki gbogbo wọn gbaruku ti ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin ki gbogbo Yoruba ba le ma fi ohun kan sọrọ gẹgẹbi ẹya nla kan ninu ile Naijiria.

Ọgbẹni Okunowo wa sọ pe Dokita Majẹkodunmi jẹ mose ti asiko yi fun awọn Yoruba gẹgẹbi alaye ọgbẹni Okunowo o ni Mose ijọni tabi ti atijọ ni o yan lati gba awọn ọmọ Israel kuro ni ẹru eyiti awọn nji lọwọ Ọba Farao tiṣe Ọba Egypt.

Akowe Agba ẹgbẹ na wa tun ṣe alaye pe Oloye H. O Davies ti o jẹ akowe gbogbo gbo o ẹgbẹ na ti o tun jẹ Minista ninu ile Igbimọ Asofin ti Apapọ pe bi a ba kiyesi iṣe rere ti a ti ọmọ woli Hezekiah ṣe ninu Bibeli Mimọ o wa sọ pe bi Yoruba ba ṣe orire lati ni awọn alagbara yi larin wa, a ṣe ileri pe on yio ṣe agbara ti gbogbo awọn asiwaju ẹgbẹ na yio fi wa ba awọn sọrọ ni ọjọ iwaju.

Ọgbẹni A Lamidi ti o ṣe alaga ọjọ na fi kun ọrọ akọwe agba ti o sọ o ni iyanju ti awọn Ọba ati Ijoye ngba lori ọrọ Yoruba di ọkan ni ijọ ki nwọn da ẹgbẹ ọmọ Ọlofin silẹ o si wa gbadura ki ẹgbẹ na le ma dagba siwaju ati si iwaju.

Ọgbẹni Lamidi wa rọ gbogbo ọmọ Yoruba Lọkunrin, Lobinrin Lomode ati agba ki wọn gbagbe gbogbo ede aiyede ti ẹhin wa ki surumọ ẹgbẹ ọmọ ọlọfin ni otitọ ati ododo ki awọn iran ti a ati bi ma ba fi wa ṣẹ epe, o tun sọ pe a fi ọmọ ale ni yio gbagbe ilẹ baba rẹ, gbogbo awọn enia ti a wa ṣe iferi pe, awọn yio sa gbogbo agbara awọn lati ri pe alafia ati ifọkanbalẹ wa fun gbogbo Yoruba.

Gbogbo ijọ' o na wa dupẹ lọwọ ẹgbẹ ti Okunọwọ fun bi o ti la wọn lọye itumọ ti ẹgbẹ na ṣe waiye wọn tun rọ ọgbẹni Okunowo ko ma ti simo lati lọ kakiri ki o si ma kọ awọn enia ti ko ti mọ itumọ ti nwọn fi da ẹgbẹ na silẹ.

Nwọn wa rọ ọgbẹni Okunowo, ki o ma fi ọju kan adugbo awọn tigbakigba. Gbogbo won kelohun raara pe, ỌLỌFIN LONI WA. ati emi gigun fun Majekodunmi, ni ipari ipade na ọgbẹni Okunọwọ dupẹ lọwọ awọn ti o wa si ipade na.

# Ẹgbẹrun Ọmọ UPGA Sa Kuro Ni'lu

IBADAN:- Ninu irohin kan to de ọwọ wa ni ọjọ Ẹti ti ṣe ọjọ kẹtala oṣu yi fi ye wa pe o le ni ẹgbẹrun (1,000) awọn ọmọ ẹgbẹ itẹsiwaju ti nwon ti sa kuro nile wọn ti nwọn ti lọ wa abo fun ara wọn ni Ibadan ati Eko lati sa asala fun ẹmi wọn lori iya ti ẹgbẹ Dẹmọ ti nṣe akoso Ijọba Ipinle Iwọ Orun fẹ fi ma jẹ awọn enia na tabi ki nwọn ma ṣi olu wọn lọna ti ko tọ.

Irohin na tun fi ye wa pe ohunti o mu awọn ọmọ ẹgbẹ itẹsiwaju (UPGA) na sa kuro ni ile wọn ni iya ti awọn ẹgbẹ Dẹmọ fi nfẹ wọn tabi pe ki nwọn fi ọlọpa ti Ijọba ibilẹ Wolewole ati awọn Oniwe Ori ma mu wọn lọna ti ko tọ eyiti o jẹ pe lọna bẹ ni eyiti ko mọwọ ti ko mẹṣẹ ngba di ero ẹwọn ti awọn oniwe ori yio tun ma bere iwe ori ti ọdun mẹwa lọwọ ọmọ ẹgbẹ Oṣelu ti ko ba ti jẹ ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ.

Ninu irohin to jade lati ọwọ ẹgbẹ ọdọ Okkpara eyi ti akowe ẹgbẹ na Ọgbeni S R A Olowolagba fi ọwọ si ni awọn ọmọ ẹgbẹ na ti ṣe alaye pe nigbati nwọn ka awọn enia ni eyiti ipin lẹ na ni nwọn ri mọ pe ẹgbẹrun (1000) awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA ni ẹkun Ilesha ki Ire Ogbomọsho, Ile-Ifẹ Ẹde, Oshogbo ati Ẹffon Asiye ni Ẹkun Ekiti lo ti alkuro ni ile wọn lati sasala fun ẹmi wọn lọwọ ẹgbẹ Dẹmo.

Ninu awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA ti nwon le ni ẹgbẹrun yin tio sa lo si ilu Ibadan ati Eko lati lo da abo bo ara wọn lori aisi ifo anbalẹ Ijoba rere to wa ni Ipinle Iwo Orun Naijiria ti ẹgbẹ Dẹmo nṣe eto akoso Ijọba rẹ bayi.

Ọgbẹni Olowolagbara tun ṣe alaye ninu irohin na pe on jẹ alaga ẹgbẹ ọdọ Okpara fun ẹkun Ilesha ni onwa ni ilu Eko bayi lati ba da abo bo ara on lori iya ti ẹgbẹ Dẹmo ti ti jẹ on nipa peki nwon ma bi ju on s'ẹwon lisi ẹṣẹ kan ti on ṣẹ ati pe ki awọn janduku ẹgbẹ Dẹmo ma ba lu on pa ni o mu on kurọ ni ilu ti on si ti on kuro ni ilu ti nwon ti bi on si ti on si lọ si Eko lati ro da abo bo ẹra on lori iya alainidi ti ẹgbẹ Dẹmọ fi iyẹ awọn ọmọ ẹgbẹ itẹsiwaju UPGA ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria bayi.

Ni ipari awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ Okpara tun ṣe alaye pe gbogbo iwa ibi ti ẹgbẹ Dẹmọ nhu bayi yio d'opin ti nwọn ba le ti dibo si ile Igbimọ asofin Ijọba Ipinle Iwọ Orun eyiti ẹgbẹ UPGA yio ṣe akoso Ijọba na lagbara Ọlọrun.

